Mo fi Ẹni ti ẹmi Muhammad n bẹ lọwọ Rẹ bura, ẹnikẹni ko nii gbọ́ nipa mi ninu ìjọ yìí, Juu ni tabi Nasara, lẹyin naa o wa ku ti ko si ni igbagbọ pẹlu nnkan ti wọn fi ran mi, afi ko wa ninu awọn ara ina

Lati ọdọ Abu Huraira- ki Ọlọhun yọnu si i- lati ọdọ ojisẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- o sọ pe: "Mo fi Ẹni ti ẹmi Muhammad n bẹ lọwọ Rẹ bura, ẹnikẹni ko nii gbọ́ nipa mi ninu ìjọ yìí, Juu ni tabi Nasara, lẹyin naa o wa ku ti ko si ni igbagbọ pẹlu nnkan ti wọn fi ran mi, afi ko wa ninu awọn ara ina".

[O ni alaafia] [Muslim gba a wa]

Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n bura pẹlu Ọlọhun pe ẹnikẹni ko nii gbọ́ nipa oun ninu ìjọ yìí, Juu ni tabi Nasara tabi ẹni ti o yatọ si awọn mejeeji, ti ipepe Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- de etiigbọ rẹ, lẹyin naa o wa ku ti ko si ni igbagbọ ninu rẹ afi ki o wa ninu awọn ara ina ti o maa ṣe gbere nibẹ lailai.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3272